IROHIN IMỌLẸ

IMỌLE *ORE AIYE TENI* GBOGBO LAWA

No 1,585 TUESDAY DECEMBER 14, 1965 (2D)

Ẹgbẹ Alagbelebu Pupa Fẹ Kọ Awon Afọju L'Eko

ỌYỌ:— Awọn ẹgbẹ Alagbelebu Pupa (Ọyọ Red Cross) ti ilu Ọyọ ti ṣe eto tuntun fun awọn afọju ti o wa ni Ọyọ ati agbegbe rẹ, eyiti yio le jẹki awọn na gbadun ẹmi nwọn ti nwọn yio fi bọ lọwọ airiṣẹ ati airimu paapa nwọn yio le maa gbe ile to dara ti nwọn ko ni maa sun Ita ati pe, nwọn ko ni tun ni ma a ṣagbe jẹun mọ.

Ninu ipade nla kan ti nwọn ṣe ni Ọyọ laipẹ yi ni nwọn ti ṣe ipinnu na pe, gbogbo awọn afọju ti o wa ni Ọyọ ati agbegbe re ni awọn yio ko lọ si ilu Ogbomoshọ ati Ikẹja nibiti nwọn yio ti lọ kọ iṣẹ ọwọ ati ti agbẹ ṣiṣe pẹlu. Nwọn ni nipa ṣiṣe bayi, awọn afọju yio le maa ṣe iṣẹ ọwọ, oko riro, agbọn hihun, igba finfin ati oriṣiriṣi iṣẹ ọwọ eyiti yio mu ọwọ wa fun Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun atipe, awọn afọju na yio le maa gbọ igbe aiye ti o dara pẹlu awọn ohun meremere fun igbadun ẹmi wọn.

Ẹgbẹ Alagbelebu Pupa tun sọ pe, lati igbati awọn ti da ẹgbẹ na silẹ ete awọn ni lati da abo bo alafia gbogbo enia, ki o maa si pe, ebi npa awọn kan nitoripe arawọn ko pe tabi nwọn ni abuku lara,

Iṣẹ awọn ni lati ri pe, awọn nfẹ gẹgẹbi ohun ti o le mu igbadun ba gbogbo enia, ki alafia wa fun gbogbo enia ki airiṣẹ le dinku ati pe, awọn yio ri pe, awọn ileri ati eto ti awọn ṣe silẹ ṣe lori irọrun fun gbogbo enia yala alara're ni o tabi arẹ ra pe.

ỌBA KAN ATI AWỌN ẸBI RẸ SA KURO N'ILU

EKITI:- Ninu opin ọse to koja lo yi ni Ọlanbiwonnu Adeyoye Onire ti ilu Ire-Ekiti ni ẹkun Ondo pelu awon ebi re sa kuro nilu won lati sa asala fun emi won eyiti oba na pelu awon ebi re fi sa lo si ilu Ibadan lati lo da abo bo ara won lori rogbodiyan to nsele ni ilu won ti o fi je wipe awon enia kan ti gbero lati pa ọba na.

Ninu irohin ti o de owo wa ni a ti gbo wipe awon enia kan ni nwon sọ fun pe ki o te te yara fi ilu na silẹ lati lo wa ibiti yio maa gbe tabi ki o fi emi re tan ti o ba mo wipe on ko le fi ilu na sile

Ninu esun ti awon enia na fi kan oba Adeyoye Onire ti ilu Ire-Ekiti ni nwon ti ṣe alaye pe ilu Ire silẹ lati lọ si ibi ipade kan ni ilu Ibadan eyiti iṣe ipade ti awon egbe Demo (NNDP) pe ati pe oba Adeyoye si je okan ni nu egbe Demo

Irohin tun fi ye wa pe nigbati oba na pada de si ilu Ire ni awon enia kan ti ise omo egbe oselu kan ba so fun oba Adeyoye pe ki on pelu ebi re yara pa lẹ eru won mo ki pada si ilu Ibadan lati lo ma gbe ni ilu Ibadan pelu awon ebi re ati pe ki nwon mase pada si ilu Ire Ekiti

Irohin tun fi ye wa pe ni oru ọganjọ ni Ọba Adeyoye Onire ti ilu Ire-Ekiti palẹ ẹru rẹ mọ ti o si kuro ni ilu na lati lọ ma gbe ni Ibadan, ṣugbọn nigbati awọn enia na ri awọn ẹbi ọba na ti nwọn tun ng e ni ilu na ni nwọn bẹrẹsi halẹ mọ wọn pe kini nwọn nṣe ni ilu? oti pe ki awọn tete palẹ ẹru wọn mọ tabi pe ki nwọn fi ẹmi wọn tan.

Oniwe irohin wa to wa ni ẹkun Ondo fi ye wa pe gbogbo awọn ọmọ, iyawo ati awọn ibatan to ba ọba na rgbe bayi ni nwọn ti ko ẹru ti nwọn si ti sa kuro ni ilu Ire ti nwọn si ti salọ lati lọ da abo bo ara wọn.

Ṣugbọn iroh n kan ti o de ọwọ oniwe irohin wa labẹlẹ pe awọn ẹbi ọba na ti lọ sa pamọ si inu ile kan eyiti o jẹ wipe nwọn ko fẹ ki enia mọ ni ilu kan ni Ado-Ekiti lati lọ da abo bo ara wọn.

Irohin tun fi ye wa pe awọn enia na ti tun ki ye wa pe ...ọ o ayọ kẹlẹ ti iṣe ti ọba Onire ti ilu Ire ni awọn enia na ti tun dana sun eyi ti o fi jẹ wipe gbogbo mọto na lo jo na rau-rau ti ko si le ṣe tunṣe mọ ni ilu kan ti a npe ni Eg si Igba Ire-Ekiti.

Ninu irohin kan to tun de ọwọ wa ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu yi ni a ti gbọ pe awọn enia kan tun lọ dana sun ile ẹjọ ti Ijọba ibilẹ onipo kẹta ti ilu Aro-mokan abuleko kan ti ko jinna si Ado-Ekiti eyiti o jẹ wipe awọn Ọlọpa ko ti mọ awọn eniti o dana sun ile ẹjọ ti Ijọba Ibilẹ na.

Ṣugbọn ọkan ninu awọn enia ilu na fi ye oniwe irohin wa pe ninu awọn janduku ọmọ ẹgbẹ Oṣelu lo lọ dana sun ile ẹjọ na.

Oniwe irohin wa tun fi ye wa ninu irohin rẹ pe ki ṣẹlẹ ina na to ṣẹlẹ ni awọn janduku ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ Oṣelu kan lo gbe Egungun ti nwọn si yi ilu na ka eyiji o fi jẹ wipe ko pẹ pupọ na ni ina nla na ṣẹlẹ ti o fi jo gbogbo ile ejọ ti Ijọba ibilẹ ilu na tan.

Ninu ọrọ oniwe irohin wa to wa ni ẹkun Ekiti ni o ti ṣe alaye pe ohunti o nṣẹlẹ ni agbegbe ilu na ko ṣe fi ẹnu sọ bayi ati pe Ọkẹ-aimọye awọn ile to wa ni ẹkun Ekiti lo jẹ wipe nwọn ti dana sun ati pe ọpọlọpọ enia lo ti padanu ẹmi lẹri iṣẹlẹ to nṣẹlẹ nipa abayọri idibo si ile Igbimọ Asofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ orun Naijiria to kọja yi eyiti awọn ena na fi aake kọri pe awọn ko dibo fun ẹgbẹ Dẹmọ ati pe awọn ko tun fẹ ki ẹgbẹ Dẹmọ tun se akoso Ijọba le wọn lori fun ọdun marun.

Alaga Eko, Ẹ ma ku Alejo o

Aworan oke yi ni ti Ọgbẹni Polak ati Ọgbẹni Dawodu

EKO:- Ni opin ọsẹ ti o kọja lọ yi ni Ọlọla M. J. Rosenbert Polak ẹnitiiṣe Asoju Ijọba Orilẹ ede Netherlands ni Naijiria ṣe abẹwo lọ si ọdọ Ọgbẹni Ganiyu Dawodu, Alaga Igbimọ Ijọba Ibilẹ Eko ninu ile iṣẹ rẹ.

Ọgbẹni Dawodu ṣẹ alaye fun ọlọla Polak wipe Ijọba on ti se eto silẹ nisisiyi lati tun gbogbo ilu Eko ṣe fun idagbosoke iṣẹ Aje ati fun anfani gbogbo awọn ara ilu.

Lẹhinti awọn mejeji fi ọrọ jẹ omitoro ọrọ tan ni nwọn ba rin kakiri inu ile iṣẹ na ti awọn mejeji na si fi ayọ tuka.

ILANA OFIN ATI ETO ẸGBẸ IJINLẸ YORUBA

Tẹni ni tẹni akisa ni ti ile ina. Oigba ni i-si pe igba rẹ l'aakaragba, ki awọn to i-fi ba a ko'le. Awa mọ daju pe ede Yoruba wa yii kun, odun, o ṣe pataki, o l'arinrin, o si jọju gidigidi to bẹẹ ti o fi jẹ pe iye awọn ọmọ ilẹ Yoruba ti nsọ ede ko din ni ẹedẹgbẹta ọkẹ (10,000,000) nisisiyi. Ṣugbọn, pẹlu bẹẹ, a wo'ye pe, gẹgẹ bi ede Gẹẹsi ti di ajumọlo jakejado ilẹ Naijiria, ede na a ti bẹrẹ si gba aiye lọwọ ede abinibi tiwa, a si fura pe, bi a ko ba di amure wa giri, ki a tete ko itara si Yoruba ti i-ṣe ajogunba wa, ede Gẹẹsi yio ko iparun ba a patipata lẹhinwa ọla; awọn ọmọ Ọdọdun yio si di eni ti nfọ ede Gẹẹsi nigbagbogbo laimọ ede tiwa rara mọ. Ki o ma ba ri bẹẹ a ṣe ipade akanṣe kan, ni ilu Eko, ni irọlẹ ọjọ kejilelogun oṣu kerin ọdun 1965. (22/4/56) lori aayan ati eto fun itesiwaju ede Yoruba.

Ni ipade naa, a fohunṣọkan lati da ẹgbẹ kan sile fun aayan ati eto yii

ORUKO EGBE:

Ẹgbẹ yii yio maa je ẸGBẸ IJINLẸ YORUBA (ẸKA ẸKỌ) eyi naa, ni yio maa ṣe orukọ ati apele re pẹlu

Aniyan Ati Afojusi Ẹgbẹ:

Awọn nkan ti Ẹgbẹ yii yio ma a lepa n'iwọnyi:
(i) ki ede Yoruba tẹ atẹniwaju de ipo pataki pe ao ma a lo o ni ipade Iwọ Oorun Naijiria fun ọrọ sisọ ni ipade awọn aṣofin ati ipade awọn ọbaloba ati fun akọsilẹ ati ikede iroh'n awọn ipade wọnyi,
(ii) ki o di aṣa baraku fun gbogbo awọn ọmọ ilẹ Yoruba, bi o ti wu ki ẹkọ iwe wọn o ga to, pe laarin ogede ara won, nigbagbogbo ojulowo ede Yoruba ni awọn yio ma a fọ, laisi amulumala fifi ede Gẹẹsi lu ede tiwa
(iii) ki gbogbo awọn aṣa dara-dara to jẹ adaiyeba ni ilẹ Yoruba o ma a tẹ'siwaju
(iv) ki imọlẹ ẹwa ede ati aṣa Yoruba o ma tan ni yoo ni ilẹ Naijiria ati tan ilẹ okeere pẹlu

Awọn Ọmọ Ẹgbẹ

(i) Enikẹni t'o ba ti je ọmọ ilẹ Yoruba yala ọkunrin tabi obinrin ti ọdun ori rẹ si ti to ọdun merindilogun le wọ Ẹgbẹ yii
(ii) Ọmọ ẹgbẹ t'o ba ṣe ṣe wọ ẹgbẹ gbọdọ fi ẹnu ara rẹ sọ fun ẹgbẹ ni ipade kinni t'o ba wa pe ile inu oun ni lati je ọmọ ẹgbẹ ati pe oun yio ma a pa gbogbo ofin ẹgbẹ mọ. Akọwe Ẹgbẹ yio si kọ orukọ ọmọ ẹgbẹ naa sinu iwe Ẹgbẹ lọju gbogbo awujọ ẹgbẹ

AWỌN OJIṢẸ ẸGBẸ

Ẹgbẹ yio yan awọn ẹni ti yẹ si awọn ipo oye ojiṣẹ wọnyi ni ipade ajọdun lọdọọdun pẹlu ibo didi ni aṣiri

1 Alaga
2 Igbakeji Alaga
3 Akọwe Ẹgbẹ
4 Igbakeji Akọwe
5 Akapo
6 Akede Ẹgbẹ
7 Oluto (Ẹleri Akapo ti bi Asero)
8 Onimoran Kinni
9 Onimoran Keji

ATOTO; ARERE O!

Eyi ni lati kede fun gbogbo eniyan papajulọ, awọn ọmọ ẹgbẹ wipe ipade ẹgbẹ "IJINLẸ YORUBA" yio ṣe ipade won ni ọjọ ọjọ'Bọ ti iṣe ọjọ kerindinlogun oṣu yi ninu ile ẹkọ giga (GASKIYA COLLEGE) ni Herbert Macaulay Street, Yaba ni deede agogo marun irọlẹ ti Ab; Alaga, Dokita Adebo ye Babal la

ETO IPADE

A bẹ gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ wipe ki awọn ma sa lai wa si ipade ọjọ na nitori pe awọn ohun pataki ti ao sọrọ le lori nipa ILANA OFIN ATI ETO ẸGBẸ eyi ti a fe ka si etigbọ gbogbo eni.

Ẹ jọwọ ki ẹ tete de ki ẹ si tun mu awọn ọre nyin lọwọ wa nigba ti ẹ ba nbọ

IRE O

Ọladipọ Yemitan
Akọwe Ẹgbẹ

Ipade

IPADE GBOGBOGBOO

Ẹgbẹ yio ma a ṣe Ipade Gbogbogboo ni irọlẹ ọjọ ọjọ Bọ to ba kẹhin ninu oṣu kọọkan

IPADE AJỌDUN

Ẹgbẹ yio ṣe Ipade Ajọdun ni irọlẹ ọjọ Ọjọ Bọ to ba kẹhin ninu oṣu April eyini ni oṣu kerin ọdun Ni ipade yi awọn ojiṣẹ Ẹgbẹ nikọọkan yio fun Ẹgbẹ ni irohin iṣẹ ti awọn ti ṣe ninu oṣu mejila to ṣẹṣẹ pari

IPADE IGBIMỌ TẸKOTO

O kere tan Igbimọ yi yio ma a ṣe ipade lẹkan lo ṣu

IPADA GBOGBOGBOO NI PAJAWIRI: Igbimọ ẹgbẹ le pe ipade gbogbogboo ni pajawiri ṣugbọn ọjọ mẹta gedegbe gbọdọ wa laarin ọjọ ti a fi lẹta ipenisipade ranṣẹ ni pọọṣi ofiis ati ọjọ ipade pajawiri naa gan-an.

6. KOṢEMANI NI IPADE:
(i) Fun ipade Gbogbogboo iye ọmọ-ẹgbẹ ti yio ma a jẹ koṣeemani ni ida mẹrin apapọ iye awọn ọmọ-ẹgbẹ ti o si ni orukọ ninu iwe Ẹgbẹ lọwọlọwọ.
(ii) Fun ipade Igbimọ Alaga tabi Igbakeji Alaga ati Akọwe Ẹgbẹ tabi Igbakeji re ati awọn ojiṣẹ ẹgbẹ mẹta miran yio ma a jẹ koṣeemani.

IDAWO: O kere tan ọmọ – ẹgbẹ kọọkan gbọdọ da sile kan losoosu sinu apo Ẹgbẹ, ṣugbọn inu Ẹgbẹ yio dun si i ni, bi awọn ọmọ ẹgbẹ ba nda ju iye yi lọ tifẹtifẹ losoosu gẹgẹbi anfani ati agbara wọn ba ti to.

ITỌJU OWO: [i] Iye owo ti Akapo le tọju s'ọwọ ko gbọdọ ti igba kan pọ ju pọun marun lọ.

(ii) Gbogbo owo ti o ba ku gbọdọ wa ni Bank ti Igbimọ Tẹkoto ba yan, ṣugbọn o gbọdọ je Banki pataki ti o l'ẹsọ ile.

(iii) Awọn t'o le fi ọwọ si iwe ṣẹẹki lati owo ni Alaga Akapo, ati Akọwe Ẹgbẹ tabi eni meji ninu wọn bi ẹse awọn mẹtẹẹta ko ba pe.

FIFI IYA JẸ ARUFIN ẸGBẸ

Ti Ẹgbẹ ba ti kin Igbimọ lẹhin ni ipade Gbogbogboo, Igbimọ le mu aba rẹ ṣe lori fifi iru iya to ba yẹ jẹ ọmọ ẹgbẹ ti Igbimọ ba ka si arufin ẹgbẹ ti Igbimọ si ti fi ẹjọ rẹ sun Ẹgbẹ ni Ipade Gbogbogboo

ṢIṢE ATUNṢE NINU ILANA YI

Ki a to yi ohun kankan pada ninu ilana yi
1 Ọmọ ẹgbẹ kan gbọdọ fi lẹta fun Akọwe ẹgbẹ ni pa aba atunṣe na
2 Akọwe Ẹgbẹ gbọdọ ka lẹta na si etigbọ Ipade Gbogbogboo
3 Ẹgbẹ gbọdọ da ọrọ na ro, ki ida meji ninu mẹta iye apapọ ọmọ ẹgbẹ o si fọwọsi aba na a

ẸGBẸ IJINLẸ YORUBA

Adura ibẹrẹ pade: Olodumare, ipade wa oni,
Ko tu wa Aṣẹ
K'o ba Aṣẹ
Ka ma ṣe aṣeti Aṣẹ
Ka ma ṣi aṣetẹ Aṣẹ
Ka le wa r'oju Aṣẹ
K'ọna wa r'aye Aṣẹ
Awa ọmọ ẹgbẹ t'o wa nihin, k'o ti ṣọ
'Ẹ ṣọ wa o Aṣẹ
Awọn ti ko i de, ki awọn de o Aṣẹ

WO OJU EWE KARUN

Iwe si Olotu Irohin Imole

A Tun Nfẹ Itan Miran

Idunnu mi ni yio jẹ bi Olotu iwe Irohin Imọlẹ ba le gba mi laye lati dupẹ lọwọ Ọgbẹni Shoyinka onitan ajiran ati awọn oku fun awọn itan alarinrin ti o maa nsọ ninu iwe Irohin Imọlẹ nigba gbogbo ti o maa fi nda wa lara ya eyiti o kun fun ọgbọn, imọ, ẹkọ, laakaye, oye ati ọgbọn ijinle

Ọgbẹni J. O. Shoyinka

Itan ti Ọgbẹni Shoyinka nsọ lọ lowo yi eyiti a nka lo ko ti sọ tan rara ṣugbọn a ko mọ ohunti o se ti a ko tun fi gbọ itan na mọ ninu iwe Irohin Imọlẹ tabi Ọgbẹni Shoyinka kọ itan na ransẹ si Olotu, Olotu ni ko tẹ itan na jade fun wa ni?

Inu wa yio dun lọpọlọpọ bi ọgbẹni Shoyinka bale pari itan na eyiti o ti nsọ lọ ni nkan bi osu me ji sẹhin

Bi o ba si ṣe wipe Ogbẹni Shoyinka ba sọ itan na ni ẹjọwọ atun nfẹ itan miran lati ọdọ nyin laipẹ bi oba tilẹ le baamu a nfẹ itan na ki ọdun yi to pari tabi ti o ba ti di ibẹrẹ ọdun ti mbọ yi ki o le jẹ wi pe itan tuntun ni ẹ o fi bẹrẹ ọdun tuntun ki o wa jẹ wipe ọdun tuutuu itan tuntun

Olotu mo du ẹ aye ti e gba mi ninu iwe Irohin nyin ki Olọrun jẹ ki ọdun tuntun na de ba gbogbo wa layọ ati Alafia

Emi ni
Owọade Alabi
COTONU

Edet O di Owo Nyin

Olotu Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye die ninu iwe nyin to kun fun ọgbon ati oye lati kesi oga agba awọn Ọlọpa ti apapọ ile Naijiria Ọgbẹni L. O. Edet nipa iwa ti awọn Ọlọpa ti nwọn ko wa si Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lati Ipinlẹ Ariwa ile Naijiria eyiti o jẹ wipe ki iṣe iṣẹ rere ni awọn Ọlọpa na wa ṣe ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Eleyi ti fi han gbangba pe iṣe awọn ja duku omo ẹgbẹ Oṣelu ni awon Ọlọpa to wa si Ipinlẹ Iwọ Orun lati Ipinlẹ Ariwa ngba ṣe ni Ipinlẹ na ati pe nwọn ko ṣe iṣe ti o tọ lori eto ofin ilẹ Naijiria eyi I oyẹ ki awọn ọlọpa na ṣe ati pe awọn ẹgbẹ oṣelu ni nwọn wa ja fun.

Eleyi yio tun jẹ ohunti o tọ ti o si yẹ bi Ọga agba awọn Ọlọpa fun orilẹ ede Naijiria ba le ṣe iwa di si akitiyan awọn Ọlọpa ti nwon ko lati Ipinlẹ Ariwa tabi pe ki nwọn tete da wọn papa nitori pe ko si ohun rere kan ti awọn ọlọpa na wa ṣe bikoṣe pe ki nwọn tun da nkan miran silẹ.

Olotu mo dupẹ pupọ fun aye ti ẹ gba mi ọkọ Ọba ko ni ṣa nyin lẹsẹ o.

Emi ni
Ọmọ Odua
IBADAN.

Mo Kan Saara Si Ọgbẹni Dawodu

Olotu, Jọwọ gba mi ni aye ranpẹ ninu iwe nyin to kun fun ọgbọn ati oye lati ki Alaga Ile Igbimọ ti Ijọba Ibilẹ Ilu Eko Ọgbẹni Ganiyu Ọlawale Daodu nipa iṣe ti o kọko ṣe nigbati o de ori aga gẹgẹbi Alaga Ijoba Ibilẹ Ilu Eko nipa to nko Malu rin oju ona Apapa eyiti Ijoba ti o nṣe Alaga rẹ tete ṣe eto lati fi moto ma ko awọn Malu na lo sibi ti nwon yio ti ma pa awon malu na.

Eleyi jẹ ohunti o wu awa to ngbe Apapa lati ri iṣẹ nla ti Ijoba Ibilẹ Eko koko ṣe lati jẹki a ri ona rin ti awọn malu da silẹ to ba di nkan bi agogo mẹfa irọlẹ ati pe ọpọlọpọ iṣẹlẹ nla lo ma nṣẹlẹ nipa ki awọn motọ ma kọlu ara wọn nitoti awọn to nda malu kọja ọna na ti nwọn ko si bikita

Imọran mi si Ijọba Ibilẹ Eko ni pe ki nwọn jẹki awọn moto yi poju gẹgẹbi o ti wa lati le fi ma ko awọn malu na lọ ona papa

Inu awa enia ti ngbe Apapa ati Surulere si dun fun iṣẹ ribiribi ti Ọgbẹni Dawodu ṣe nigbati o gba eto akoso Alaga Ijoba Ibilẹ na.

Emi ni
Tajudeen Adesanya
EKO

WANTED

Advance Apprentice and Apprentice Printers,

Apply In Person

Irohin Imolẹ's Office
16, Bamgbose Street,
LAGOS

Kere o Kere o! Akiyesi Pataki

Awa na le jẹri wipe Ojulowo hanunhanun Egbogi na LEOPILLS awa na nlo ni Gold Coast (Ankara Ghana pẹlu meji rẹ ko si ninu gbogbo orisirisi Egbogi ti o wa ni Ile Naijiria

A wa na njẹwọ ni igboro Ilu Eko, Irohin ti o wa lẹnu gbogbo enia tọmọde t'agba ni asiko yi ti nwọn fi ṣe ọrọ ati orin larin ara wọn nipa Egbogi Jamani olokiki yi ti nwọn npe ni LEOPILLS

Imọran awọn Dokita Oyinbo ti nwọn nṣe iwadi Egbogi LEOPILLS, yi kan sọ wipe bi o ti lagbara to ati bo jẹ Ojulowo giriki ati atamatase fun "JẸDIJẸDI" bi o tiwu ki ọjọ rẹ pẹ to bẹ na ni nwọn si tun fi ọwọ sọya tabi pe ileri fun gbogbo awọn ti amudi tabi iju, Igbẹ sise, aiko ri igbonsẹ deede, inuririn nigbakugba ara wiwo, Ẹsanri ẹhin didun sisan ati aiko riran kedere ko di ro buruku ara, aisan Onigbameji ati orisirisi arun miran gbogbo pẹlu

"Wipe nwọn yio ri alafia ni ki eiak ti nwọn nba egbogi LEOPILLS nitoripe o tun ma tun ẹjẹ ṣe enia nipa sis di ọtun.

RANTI PE ALAFIA LOGUN ỌRỌ IJAFARA SI LEWU PẸLU.

IYE OWO EGBOGI LEOPILLS:— Igo nla sile mẹfa abọ (6/-6 pere Igo kekere ṣile mẹta abo (3/6) pere. Bere Ojulowo Egbogi miran fun orisirisi A nta ti e ba fẹ ni Ṣọbu awọn:—

ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street, Yaba
LAGOS ISLAND CHEMIST
Victoria Street, Lagos
UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street, Lagos.

Angelina Super -- Rose

(O TI LO WA JU)

Eleyi ṣẹṣẹ jade ni ko si nita rara aṣẹṣẹ jade akan a ko mọ ibiti o lọ ohun pataki ti a mọ nipe "O ti lọ wa ju"

Super rose yi wa fun ipara gbogbo enia lọmọde lagba ọkanrin ati lobinrin o tun wa fun irun didi ati kiko olo-lu o nmu irun ọkunrin pap ma dan ki o si jọlo o ma wn ara ni ẹwa ak tun awọ ara yio jẹ yọ jade perepere fun enia dudu ba loo yio ma dan gẹgẹbi jigi enia pupa aga ṣe lyen ti wa tẹlẹ.

agTere sare w tabi ki o kọwe fun tirẹ loni ki o to tan nternational osmetic Industries" 36' Ọmọwunmi Si Iet, lehin kanCu Mushin Ẹ tọju ara ati irun nyin ẹ ne pẹlu awujẹsulọ nyin owo pọku ni 1/3d fun ẹyọ kan 15/- fun mejila ọmfun alaye si .

ITUMỌ ALA

Nwọnyi ni awọn ibere ti a ri gba. Awọn itumọ wọn ni yi Eyi si ni lati kilọ fun awọn onibere pe ki nwọn ma kọwe wọn daradara, ki a ba le ma ri i ka, enikẹni ti ko ba kọ tire rekete ko ni ri itumọ ala rẹ ka ninu Iwe.

Babatọla Olufẹmi Badagry — Ṣọra nipa irin ajo oju omi toripe iku ojiji mbẹ fun o

Amos Ojo Akure — Maṣe ba enia ja ni asiko yi, enu ọmọ enia ma ba ti ọwọ rẹ bọ

Bisiriyu Abẹokuta — Iwọ yio gba iṣẹ rere lati ọna jinjin re e, ti yio ṣe ọ ni anfani.

Samuel Sheteolu Ilaro — Okiki rẹ yio kan iaseko yi ṣugbọn ṣọra lọdọ awọn ọrẹ, ki nwọn ma ba a da si ọ lọrun

Aduke Faramọbi Lagos — Oke iṣoro rẹ yio di pẹtẹlẹ fun o. Ṣọra lọdọ orogun rẹ

Taibatu Isalẹ Eko Lagos — Ire ajẹmọnu kan de fun ọ tan oisisiyi, Ṣọra lati ma a fi nu han awọn ti o npe ni ọrẹ.

Akiyesi:- Fi ala tirẹ ranṣẹ ngo si tumọ rẹ fun ọ lọfẹ

Josefu … Ilala
P O Box 159
Mushin

YE IRAWO RE WO

AQUAIRUS (Jan 22 Feb 20) Foaji ati ifọkanbalẹ rẹ lo i yio ga jojo awọn ti o mba ọ lọpọ yio ni ifọkanbalẹ si ọ gbogẹo … işoro kẹkẹke ti o wa ni nbẹ yio yara par…

PISCES (Feb 21 Mar 20) Bi o ba le tun ara ṣe iwọ y'o gbadun gidigidi gbogbo wahala ati awọn ohun ti o ndanu rẹ yio yara kuro … akoko … lori awọn ọrẹ rẹ

ARIES Mar 21 April 20) Maṣe jẹki … arẹ mu ọ ki o si jẹki oti rẹ pa gbogbo ohunti o ni lati ni ako o yi ki o sọ ọ digba miran Pataki rẹ ni wipe ki o to … ẹmi ar… rẹ

TAURUS (April 21 May 20) Igbakan mbọ ti o jẹ wipe gbogbo ert to ng … patapata ni yio ṣe ti iwọ yio si bori awọn ohunti o jẹ ṣoro fun lọdọ awọn enia

GEMINI (May 21-June 21) Ara rẹ le ganga … to bẹ ti o fi le kapa awọn iṣoro ti o wa fun ọ ṣugbọn … o k… kọ ri pe adehun … ko si s… t tanjẹ nibẹ

CANCER (June 22 July 22) O yẹ ki … ara rẹ ṣe, bi bẹkọ nkan yio bajẹ pupọ nṣe … ki o ni s… nitori … awọn ẹgbẹ rẹ ko gbọdọ gbọ ọrọ aidara lẹnu rẹ, kuku fi ẹnu rẹ mọ ẹnu

LEO (July 23 Aug 22[Egbogi ti o be lo loni ire ni jẹ iwọ yi … si … ponkipọnki ni ara rẹ … ri iwọ yio ti irohin atata ka … ọ … yio si tẹ ọ lọrun

VIRGO (Aug 23 Sept 23) Iwọ pẹlu yio ri wipe aipe ndara fun ọ ko si tọ ki ma ṣe tabi kan mọ ipade kan ti iwọ yio ba wọn ṣe yio dun yio … ariorin b… iwọ ko ba gbe ti arino da…i

LIBRA (Sept 24 Oct 23) E… u le ma ya ọ si gbogbo bi nkan ti nlọ si fun … yi maṣe kọminu si tunbọ ṣe suru ohun ti o … yio tẹ ọ lọwọ dandan Edekoyede ti o si oṣẹlẹ labẹ ile rẹ ko ta ohun ti o le mu o ko komu laipẹ gbogbo r… yio s… lo lo

SCORPIO (Oct 24 Nov 22) Nṣe … aiye rẹ yio ma gbadu si ajo … ẹrin … ayaya … o si … ara rẹ p mo ni … oni

SAGITTARIUS (Nov 23 Dec 21) Bi o ba ngbero lati ṣe ohun … ko yi … lo ye ki o ṣe, ire wa fun ọ lona … ṣugbọn emi iwọ pa … nse l… omi b ago o si … ọ si … dẹ nis… i

CAPRICORN (Dec 22 J… 21) Ọ… ko bale nipa ohun k… n ti … ngbe … lati se, ki o m… o y… o enu bi … imod … ohun … o ṣe suru

APIAS RHUMATIC & DOGES

Ojẹ ojulowo Lanunhanun egbogi Jamani to lagbara gidi fun iwosan LAKUREGBE" to … ba enia ja

Orişirişi lakuregbe ni o wa lakuregbe Arungun ti o ma nsan enia ninu egungun ara lakuregbe ti o ma nwu enia ni ẹsẹ roboto ti o njẹki ẹsẹ wuwo lati ma rin Lakuregbe ti o ngbẹ erikerike danwo kori bi o ti roron lati lo tabi ki o ma şe ayipada ẹsẹ, ara tita bi eyiti enia fi ata obẹ pa ibadi abi egugu ara wiwo, ako iba abi pipon tabi riron.

Bi enia ko ba gbajumo lati … rẹ lasiko o le sa owo pa enia

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, Tinubu Square Lagos
Phone 282878 Nigeria, (Ọja Ita Faji
LAGOS

Iwo Ha Nfẹ Ile Eko Bi?

Room		£3
Room		£4
Room		£5
Room /	Parlour	£6
Room /	Shop	£15
Flat	(Lgos)	£20
Flat	(EB)	£25

Ti o ba nfẹ okan ninu awọn ile wọnyi yara tete lo ni Ọgbẹni ODUS:— 187 Bamgboşe Sreet Lagos ni de-de agogo mẹrin irolẹ si agogo mẹfa irọlẹ. ijafara ewu anfani nla kan ni eyi jẹ fun ọ pe … o ri ile l'Eko

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ATI OGO

NIPA **DYNAMREN** TỌNIKI

ALE-BI-ALE Egbogi Tọ jẹki amọnu tilun ti gbogbo aga ilu Eko ati jakejado Naịiiti … mọ d… jẹ fun Akr jebara ati Ajẹbidan işẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo

Bi arẹ ara ba nmu ọ, n… gbakugba fun wahala tabi işẹ şişe ti o ko le jẹun dara dara, tabi ki o male sun da da de ọkan l… san tabi awọn şaa ara rẹ gbogbo ki ṣe fun daradara ti Emi Breath inu ko ba kunlẹ daradara wọn işẹ tabi wahala sise tabi inu awọn ailera gbogbo nyin ti ọjọ ori (age) ba ti kọja ọgbọn ọdun si adọri tabi ubelọ mọ daju pe DYNAMIREN ni egbogi ti o nfẹ lati so ara di … tu … pafapata inu rẹ a j… lọ ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bi yabo dada kAra rẹ yio gbe kankan ni gugba yio sa pẹlu ioq adeubrode … iyẹn d… j ba

WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palm Church Street Lagos
Phone.- 22878 Nigeria, (Ọja Ita Faji)

BOSEDE KI GBOGBO OMODE

Mo ki Olotu
Pe o ku ipalemo odun
Oke le o ma a lo
Mo si tun ki awon
Alabaṣepo re
Paapa pe
Odun odun ni
Yio ya ab oo
Gbogbo enyin onkawe
Irohin Imole
Ni mo tun ki
Pe odun yi
A san yin sowo
A san yin somo
A san yin
S'alafia ara pelu
Mo si tun ki
Enyin omo keekeeke
Elegbemi paajulo
Enyin omo ile iwe
Jakejado Naijiria
Pe e ku ipalemo
Odun O
E o ma mo iwe yin
Gbomogbomo ko ni
Ji yin gbe o

X X X X X

E ko ni ṣaaku
Mo awon obi yin
Loju
Ki ngto ma ba
Oro mi bo
O yeki njuba
Awon onkawe
Pelu baba to bi mi lomo

X X X X X

Toripe adaṣe
Ni i hun ni
Iba ki i
Hun enia
Awon baba wa
Ni i maa pa
Lowe bayi pe
"Omo ti Gambari
Ba bi
Okun ni i yio ran
Toto o ṣebi
Owe o
Ise baba mi ni mo gbowo le
Iba baba mi
To fi kalam a
Le mi lowo
Pe ki ngma ko o
O ti gbadura
Fun mi pe
Nko ni ṣi i ko
Iba enia ati Olorun

X X X XX

Ta o, e nle mbun O
Enyin omo ile iwe
Elegbe mi l'Okuorin
Mo ki nyin leekansi
Pe e ku ipalemo Odun
Jesu Kristi Oluwa
Ti a npa emo de
Ojo ibi Re ki ṣe
Onijagid jagan enia
Tori tidi eyi
E maṣe ja l'ojo odun
[illegible]

E maṣe ju "bisiko"
Lu enia
E maṣe na omo—olomo
Ni Koboko
E maṣe koegbe
Yago f'eṣu jo

X X X X X

Onirele ni
Jesu iṣe ati omo Olorun
Ni owuro ojo
Keresimesi
E lo we
Ki e si mu
Aṣo to dara si ara
Lebinna ki e
Lo si Ṣooṣi
Lo sin Eleda yin
Ki orin ayo yi
Si gbenu yin kan
Lojo na bayi pe
"Ode Kristi Oluwa
Lati ibugbe Re lorun
Lati ite alafia
O wa si aginju wa
2, Alade Alafia
De lati ru ponju wa
O de lati fi imole
Le okun oru wa lo
Alafia Oluwa
Ki o ma ba
Enyin ati awon obi yin gbe
Lailai ati titi lailai
A-m-i-n

Lati Oju Ewe Keji

Awon ti ko ni i.....le wa, ki
iso Re t'o fi nṣo wa nihin
ki o fi ma a ṣo won nibiki
bi ti nwon ba wa Aṣe
Eyi ti a wi yi,
Edumare, jo ki o ṣe o! Aṣe
Adura ipari ipade:
Olodumare,
A dupe fun apero wa oni;
Bi o ti yori si rere yi,
Bee bee ni ki a maa ri o
Ni ti ti eyi ti mbo
Ki oju o pe Aṣe
Ki eṣe o pele Aṣe
A....de....le....ba ire o Aṣe
A....rin na....ko ire, Aṣe
A....ko....ya ...ibi,
Aṣe, Edumare,

Angelina Super -- Rose

(O TI LO WA JU)

Eleyi ṣeṣe jade ni ko si nita rara aṣeṣe jade akan a ko mo ibiti o lo ohun pataki ti a mo nipe "O ti lo wa ju"
Super rose yi wa fun ipara gbogbo enia lomode lagba okunrin ati lobinrin o tun wa fun irun didi ati kiko olo-lu o nmu irun okunrin papa ma dan ki o si jolo o ma wn ara ni ewa akotun awo ara yio je yo jade perepere fuBi enia dudu ba loo yio ma dan gegebi jigi enia pupa aga ṣe iyen ti wa tele.
agTere sare watabi ki o kowe fun tire loni ki o to tan ni International osmetic Industries" 36' Omowunmi St 'Iet, lehin Kansalu Mushin E toju ara ati irun nyin e to ne pelu awujesulo nyia owo poku ni 1/3d fun eyo kan 15/- fun mejila wa fun alaye si.

IROHIN IMOLE

IMOLẸ ỌRẸ AIYE TẸNI GBOGBO LAWA

No 1,585 TUESDAY DECEMBER 14, 1965 (2D)

Baba Kan Ta Ararẹ Nibọn

KANO:— Ọrọ di b'olọ o ya fun mi ti Olukuluku si nsare jannajanna kakiri ti nwọn nsọ wipe ẹ f ı ni eyi a ı eedı, ni adugbo kan ni nombọ 5, Gold Coast Road, Saba ı Gari, ni ilu Kano si ọjọ ọjọ'B) ti se ọjọ kẹjọ oṣu yi nigbati baba kan ti o bi ọm) maru ı yinbọn jẹ ni Owurọ ọjọ na,

Ẹniti ọrọ na ṣe oju rẹ sọ fun oniwe irohin wa ti o wa ni ilu Kano wipe, gbara ti ilẹ ọjọ na mọ ni baba na ji ti o ki awọn iyawo, ọmọ, ọrẹ ati awọn molẹbi rẹ pe, "ẹ karọ o, ṣe daada ni ẹ ji o, ẹ si ku iṣẹ ana o, ṣe awọn ọmọde nmu Oluwa yio ba ni wo wọn o", ti awọn sişe. amin

Ọkan ninu awọn ti o ngbe inu ile na tun fi ye oniwe irohin wa ninu ifi ọrọ we ọrọ pe, ni nkan bi agogo mẹfa abọ owurọ na ni awọn ki ara wọn pe ẹ ku ' rọ o, ṣe daada ni aji o, ṣugbọn koju ọgbọn iṣẹju agogo lọ ti on gbọ ariwo ibọn ninu yara rẹ, ki on to si ilẹkun lati wo ohunti o ṣẹlẹ ninu yara baba na, oku rẹ ni on ba nilu ag' ara ẹjẹ.

Nınu aleye na ni nwọn ti sọ fun oniwe irohin wa pe, baba na to ẹni adọta ọdun, o si bi ọmọ marun o yio Ibọn oloju meji jẹ.

Irohin tun fi ye wa pe, o to oṣu mẹta ti ara baba na ko da, ti o nṣe aisan, o si de ọdọ awọn Dọkita mẹta lori aisan ti nṣe ṣugbọn ko gbadun sibẹ.

Awọn ọlọpa ilu Kano ti gbe oku Ọkunrin na ati ibọn ti o fi pa ara rẹ pẹlu awọn ọta ibọn ti nwọn ba ninu yara rẹ.

Awọn Ọlọpa si nwadi ohunti baba na ro lọkan ti o fi pa ara rẹ, atipe enia pupọ ni awọn Ọlọpa wadi ọrọ lọwọ won bayi.

IDI TI ẸGBẸ AJUNMỌṢẸPỌ KO FI LỌ PE ẸJỌ

EKO:- Ẹgbẹ Itẹsiwaju (UPGA) ṣe alaye fun oniwe irohin wa ni ọjọ Ru tise ọjọ kẹjọ osu yi pe awon ti pinnu ni ọkan awọn pe, awọn ko t n gbe ẹjọ kankan ti o ba jẹ mọ ti ibo lọ si ile ẹjọ mọ papa ibo ti nwọn di ni ọjọ kọkanla oṣu kẹwa ọdun yi eyiti ibo na bi ige ati adu bi ti ọpọlọpo ẹmi ti lọ di la'sọ ile ati mọto ti nwọn fi jona pẹlu

Alaga Ikede igbimọ ẹgbẹ Itẹsiwaju fun Ipinlẹ Iwọ Orun Oloye Victor Bisi Ọna banjọ so fun oniwe Irohin wa pe ẹgbẹ UPGA ko ni se iranlowo fun ọmọ ẹgbẹ ka kan lati lọ pe ẹjọ lori ibo ti nwọn di kọja yi nito tọ awọn m'ran nbere lọwọ wa pe ki ni ero wa lori ọna magomago ti awon ẹgbẹ Dẹmọ ni awon gba wọle ti o si han si tewe tagba ni orilẹ ede yi.

Awọn ti o ni ifẹ ẹgbẹ UPGA lọkan ti nkesi wa pe o yẹ ki awọn ti o wọle ti won ni nwon ko wọle ati awon meji ti ile iṣẹ Radio Ibadan ni o wọle ni agbegbe meji si mẹta eyiti o ru awọn loju iru awọn ọẹ o jẹ ki nwọn lọ yanju rẹ ni ile ẹjọ ati Tun gba iwe aṣọ ilẹ won ki akọwe idi eto ibo fi ọwọ si pe nwọn wọle ti awon tun gba pe nwon ko wole mọ

Gegebi ero ọkan wa a gbogbo pe ẹgbẹ Dẹmọ pẹlu awon Igbimọ eto ibo ti pa mọpọ eyiti o so o fun wa lati le bori bi yrọ ni ba de ile ẹjọ

'IPEJo'

"Bi o ti wu ki o ri a ni awọn orisirisi ọna ti awon asiwaju ẹgbẹ Itesiwaju ko fe fi lo si ile ejọ mo lori ibo ti won di kọja yi lẹna kinni a ri wipe ifi owo ati akoko t' o niye sofo,

Lati lọ si ile ọj ki a si pe ẹjọ fun ọdọrin ọmọ ẹgbẹ wa lọna kini, a le ṣ ori e pe larin ọdun meji ni nwọn y'o ṣe idajọ ninu ẹjọ na, papa bi nwọn ba se ẹjọ na larin oşu mẹrin-iel 'gun tani yio wipe ki a tun ibo agbegbe ti o jẹ adọrun na di? Ẹgbẹ Dẹmọ kanna ni

La'pe egbe Dẹmo y'o ma şofin orisirisi ni ile Igbimo Asofin ti Ipinle Iwọ Orun eyiti yio fi soro lati le maa dibo gegebi eto nwon yio se ni ọnn ti yio nira lati dibo ti o ni alafia ati ifọkan bale

"Oloye Samuel Ladoke Akintọla yio si tun wa gẹgẹ Iala koso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun, ki a wipe adọrin na tu jẹ ọmọ ẹgbẹ UPGA oh iti nwọn le ṣe ni wipe ki nwọn sọ pe, ko ni igbẹkẹle ninu rẹ mọ eyiti o han si gbogboo enia pe oloye Akintọla ko kọ ki o ku sori ipo alakoso ju wipe ki on pe o i iṣẹ silẹ

Igbagbo

"Igbagbọ wa ni wipe, ile ẹjọ ti o ṣe pataki julọ ni idajọ awọn enia lori ohun ti o de ilẹ yi awọn enia Ipinlẹ Iwọ Orun ko ṣe mu ni igan, nwọn mọ ọna ti nwọn le gba fi di ibo wọn fun awọn ẹgbẹ ti nwọn ni ifẹ si

Enia Ipinlẹ Iwọ Orun ni Ọlọrun yio ranlowọ pẹlu ifẹ inu rere wọn ni nwọn le ti mu alafia ati Ijọba ire a fun Ipinlẹ Iwọ Orun lagbara Ọlọrun awọn yio jẹki gbogbo rẹ jẹ irọrun ati alafia fun Ipinlẹ Iwọ Orun,

Oloye Bisi Ọnabanjọ tun fi awọn iwe ibo pe enia wọ e han oniwe irohin wa ey ti o kun fun aparutọ.

Angelina Super — Rose

(O TI LỌ WA JU)

Eleyi ṣẹṣẹ jade ni ko si nita rara Aşẹṣẹ jade akan ako mọ ibiti o nlọ Ohun pataki ti a mọ nipe "O ti lọ wa ju"

Super rose yi wa fun ipara gbogbo enia lọmọde lagba lọkunrin ati lobinrin O tun wa fun irun didi ati kiko olowo o nmu irun ọkunrin pap ma dan ki o si jọlo O ma fun ara ni ẹwa akotun Awọ ara ylo si yọ jade perepere.

Bi enia dudu ba loo yio ma dan gegebi jigi Enia pupa kuku ti wa tẹlẹ.

Tere sare watabi ki o kowe fun tire loni ki o to tan ni West Afican Cosmetic Industries" 35' Ọmọwunmi St Iehin District Council Mushin ẹtọju ara ati irun nyin ẹtọ Owo pọku ni 1/3d fun ẹyọ kan 15/- fun mejila

ALEBIOSU BOOKSHOP

13 BAMGBOṢE STREET, PHONE (21304) LAGOS

LADIES & GENTLEMEN/

As your problem is ours, therefore we have got in Stock, Seasonal Lovely & Interesting Xmas Cheque and Xmas Cards in assorted types as:-

To my Darling	2	To my Sweet Heart	
,, my Lover	4	,, One I Love most	
,, my Boy Friend	6	,, Husband	
,, my Wife	8	,, my Sister	
,, Brother	10	,, my Friend	

You will be mostly impressed if you come to the abo-named Bookshop for your Seasonal Greeting Cheques & Xmas Cards.

WISHING YOU HAPPY CHRISTMAS IN ADVANCE

Printed & Published by Modupẹ Printing Press (), ... Lagos Phone 2196?
Editor: TUNJI ADOBOSUN 45, Campbell Street Lagos. 14/12/65